# IWE SI OLOTU IROHIN YORUBA

## TANI O JẸBI NINU AWỌN ENIA WỌNYI ?

Mo lọ si irin ajo, mo lo to Ọsẹ mẹta ṣugbọn ki nto de ikọ ẹgbẹ mu Iya Iyawo mi ọpọlọpọ ogun ni wọn lo si ikọ yi ti ko gbosun. Ẹgbọn mi tiṣe aburo iya mi ni ọrẹ kan. Ọrẹ ẹgbọn mi yi jẹ Babalawo yọbọkọ, ọkunrin yi longe ẹgbogi fun Iya-iyawo mi na ti ikọ yi ti nfuyẹ dịẹdịẹ.

Ṣugbọn ninu yara ni Babalawo yi ti i ma nlo ogun fun Iya Iyawo mi, ki Alufa kan to wipe Eewọ! Ni gbangba l'aṣa se, Ogun kini a nlo fun onikọ ẹgbẹ lori bẹdi, nwọn sọ pe ọdẹdẹ ni onişegun gbe njoko nitoripe kosi ise ti a nṣe loko t'andoru .-

O sa, ifura ko jẹbi onişegun yi le lọ si ile Iya Iyawo mi mọ. Aṣe oju a maa ti onişegun ?

Nigbayi ni Iya Iyawo mi yi wa nran Iyawo temi si okunrun onişegun na.

Ṣe awọn Yoruba ti sọrọ tan wipe:- Iso ni olokunrun fi i dupẹ, Aṣe ṣamọ-ṣamọ Iya Iyawo mi yi ti fi ọmọ rẹ to ni yigi lori fun Babalawo yi, Babalawo na si gbe Iyawo mi salọ laija'we lai san 'fẹ t'ọmọ-t'ọmọ ti Iyawo mi bi fun mi, se ẹ nri ọdaran enia bayi o.

Larin ọdun kan si meji ti a wa wọn kiri to su wa. Iro ti ao gbọ nipe:- ọmọ ti obirin mi bi ku si wọn lọwọ nibi ti nwọn salọ Iyọrisi iṣẹ ti iya onikọ ẹgbẹ se niyi o enisi a sọpe kio ma ku, tio lọ fi ọmọ temi fun Iku pa lọdọ Babalawo, Gbajare o! kini Imọran inkan ti mo le se fun Iya oniko-ẹgbẹ na o? Asi pe tani jẹbi o?

Emi ni,
Yesufu Aṣiyanbi,
Ile Olufọn Isalẹ Oṣun

OSHOGBO

## Ẹ BA EYI YE MI ?

Olotu, Jọwọ gba mi laye diẹ ninu iwe rẹ oloyinmọmọ lati bere awọn ọrọ pataki mẹta yi lọwọ awọn ọrẹ mi to nkawe Irohin Yoruba, nitoripe awọn baba wa ni ma npa lowe wipe bere bere ki şi bere, toto o se bi owe o.

Awọn Ibere mi na ni wọnyi:-

1 Kini ohun ti o rọ to ju omi lọ ?
2 Kini ohun ti o le fo to ju ẹiyẹ ?
3 Kini ohun tio dun ni ju ọmọlẹ?

Olotu inu mi yio dun bi ẹ ba le jẹ ki awọn ọrọ wọnyi tete jade ninu Iwe ayin oloyinmọmọ, Ọkẹ Ọba ko ni ṣa nyin lẹsẹ o Iwaju ni ọpa ẹbiti nyin yio ma a re si o,

Emi ni
I. O. Aro

EBUTE-METTA.



## ABIYAMỌ BTI RẸ MELO

Abiku ọmọ nda ẹ l'amu bi ?
Awọn arun wọnyi ba ẹyọ ọmọ rẹ lẹnu bi

AIPERI
ỌRERE
INU-IWỌ
OSI
IGBONA
IKỌ
IGBẸ-ỌRIN
OTUTU
IBA
JẸDIJẸDI

ati orişirişi awọn arun miran ti ima yọ ọmọde l'ẹnu ni igba BHIN BIHU, lọ ra 'YARO' awo igba arun ọmọde ni fun gbogbo awọn arun ti ima yọ ọmọde l'ẹnu.

"YARO" ba pe meji ni gbogbo Ili Nigeria.

Ki Iwọ ki o si i pe orukọ "YARO" ni o wa lara igo na ki a ma ba ta ẹdamẹd egbogi miran fun.

EMỊ A K IWE Irohin Yoruba NIGBA-GBOGBO

O NWO EGBO SAN SA FI PA IBE



MENTHOLATUM




"Mentholatum" Fifi pa ara a ma a mu egbo ati iṣaka ara tan bi Idan o si rọrun lati lo. Ṣa fi pa ibẹ lẹsẹkẹsẹ ni "Mentholatum" ti I mu Irora kuro a si mu egbo san, gbogbo awọ ara a ma wa dan. "Mentholatum" dara fun gbogbo arun iṣaka. Ni wiwo san ati itura, Itura rẹ atun ma a mu ilera wa. Tete lọ ra idẹ tabi agolo kan loni.

Bere fun Mentholatum gan an. Eyiti o jẹ pe awọn Mentholatum Co. Ltd., (Est. 1889) Slough, England nikan ni nwọn nṣe e.

## Pataki Ọja Ti Awon Onisowọ Le Ri Ere Je Pupo Lori Rẹ Niyi

Reids Watney Stout
Reids Watney Stout
Reids Watney Stout

Ẹ tete wa ra egbogi wọnyi—

Ogun Oju (Eye Drops), Ogun Akokoro (Toothache Drops), Ogun Eti (Earache Drops), Ogun Ikọ (Fever Cough Mixtures), Ogun Igbẹ-gburu, (Diarrhoea Mixtures), Orişirişi Ogun Atẹjẹsẹ (Tonics of different kinds), Olive Oil, Extract of Malt, ati Cod Liver Oil.

Ẹ tete wa ra ọti Stout-beer ati ogun orişirişi ti o dara ju ti a si nta ni ẹdinwo yi lọdọ:—

**Messrs J, A. Ajao Brothers,**
10, & 7, Egerton Road, Lagos, Nigeria.

ILE ALAWẸ ṢE IPADE ADANŞE G C —Ni ọjọ Aiku ti işe ogunjọ oşu kinni ọdun yi ni awọn ọmọ Ile Alawẹ ṣe Ipade fun Imọran ilọsiwaju agbole wọn ati pe ki awọn ọmọ-lẹbi na le wa ni irẹpọ.

Gbogbo ẹsẹ ọmọ agbole na ni o pe lọjọ na. Nwọn si sọ ọrọ iwuri ati ilọsiwaju larin wọn, lẹhin igba ti awọn gba adura tan. Fun ọjọ meji ni awọn fi se eto na.

Alaga ijoko na ni Ọgbẹni E A Ayilara. Diẹ ninu awọn ti ẹsẹ wọn pe sibẹ ni Ọgbẹni Adeyẹmọ, E O Folorunshọ, R Alufa, B A Ajiṣafẹ, S Ọlọla, A Aderinọla ati Samuel Ajiṣafẹ. Ki Ọlọrun şe nyin lọkan o. Amin.

A L A T

